**8.** Lẹhinna dajudaju a o bi nyin lẽrè nipa idẹra ni ọjọ na.

ثُمَّ لَتُسۡـَٔلُنَّ يَوۡمَئِذٍ عَنِ ٱلنَّعِيمِ ٨

## (103) Suratul - 'Asri

سُورَةُ العَصۡرِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Mo fi akoko irọ̀lẹ ('Asri) bura.

وَٱلۡعَصۡرِ ١

**2.** Dajudaju enia mbẹ ninu òfò.

إِنَّ ٱلۡإِنسَٰنَ لَفِي خُسۡرٍ ٢

**3.** Ayafi awọn ẹniti nwọn jẹ onigbagbọ (ododo) ti nwọn si ṣe iṣẹ rere ti nwọn si ngba ara wọn niyanju ṣiṣọ ododo, nwọn si ngba awọn enia niyanju lati ni farada.

إِلَّا ٱلَّذِينَ ءَامَنُواْ وَعَمِلُواْ ٱلصَّٰلِحَٰتِ وَتَوَاصَوۡاْ
بِٱلۡحَقِّ وَتَوَاصَوۡاْ بِٱلصَّبۡرِ ٣

## (104) Suratul - Humasah

سُورَةُ الهُمَزَةِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Egbe ki o ma ba gbogbo abuni loju ẹni (Humasah) ati abuni lẹhin.

وَيۡلٞ لِّكُلِّ هُمَزَةٖ لُّمَزَةٍ ١

**2.** Ẹniti o ko owó jọ ti o si nka a laka-tunka.

ٱلَّذِي جَمَعَ مَالٗا وَعَدَّدَهُۥ ٢

**3.** Ti o nro pe owo on ni yio mu on ṣe gbere laiye.

يَحۡسَبُ أَنَّ مَالَهُۥٓ أَخۡلَدَهُۥ ٣

**4.** Rara o, dajudaju a o fi sọ̀kò sinu ina Hutamatu.

كَلَّاۖ لَيُنۢبَذَنَّ فِي ٱلۡحُطَمَةِ ٤

**5.** Atipe kini ohun ti o le fi ina Hutamatu nã mọ ọ?

وَمَآ أَدۡرَىٰكَ مَا ٱلۡحُطَمَةُ ٥